# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

### ESI ỌRỌ YESUFU AṢIN-YANBI

Esi ti mo ri pe mo le fi si ibere Ọgbẹni Yesufu Aṣiyanbi gẹgẹ bi imọran temi nipa ibere rẹ ti a jade ninu Iwe Irohin Yoruba ti 17/3/52 ri pe ki o lọ pe babalawo, iya iyawo ati iyawo l'ọjọ pe awọn pe on l'ọmọ, awọn mẹtẹta yen ni o jẹbi ọrọ na.

Mo dupe aye ti e gbami.

Emi ni
S. A. Ọlerunlogbon
Mapo—Hill,—IBADAN

(2)

O'otu, jọwọ gba mi laye lati ṣe alaiye kekere yi fun Ọgbẹni Yesufu Aṣiyanbi nipa ibere rẹ ti ọjọ 17/3/52 ti o sọ pe nigba ti on ko si nile ti iya iyawo on ko gbadun, ti iya iyawo na wa fi obinrin on fun oniṣegun.

Alaye ti emi le ṣe ti ori ọrọ na ni pe iya iyawo rẹ ko jẹbi rara nitori pe nigba ti oniṣegun ba sọ fun un pe bi ko ba fi ọmọ rẹ fun on ko ni gbadun emi ro pe ohun ti o fa ti o fi ṣe bẹ ni yen. Nipa ti ọmọ ti o fun oniṣegun. Ọmọ papa ko jẹbi rara nitori ko ni lẹ ki iya on o ku laisidi.

Babalawo yen ni o ni ẹbi na idi rẹ nipe on paapa mọ pe obinrin yi ni ọkọ ti o fi gbee salọ on paapa fihan pe ole ni on ja, nje bayen ni nwọn gbe iyawo? Babalawo ni ki o mu dada ati pe on ni o ni ẹbi ọ.

Emi ni
Sitta
JOS.

(3)

Nipa ibere "Tani o jẹbi ninu awọn enia wenyi" ti o jade ninu Iwe Irohin akọmọ'ọgbọn ti oṣu Aje ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu ti o kọja yi, inu mi yio dun pupọ, ma a si dupẹ bi ẹ ba le gba mi laye diẹ ninu Iwe nyin na lati dahun ibere Ọgbẹni Yesufu Aṣiyanbi na.

Iyawo rẹ lo jẹbi nitori a ti pe ajo iya rẹ lo se fẹ oniṣegun, nigbati oniṣegun na wa gbe e lọ, o ti ṣe le fẹye tọju iya re toti tori re fẹ oniṣegun? Awọn baba wa ni mra pa owe pe "Eni ti a kọ ni ika to nyọ, o ti ni ika se tẹlẹ ni, toto o.

Iyawo rẹ ni ko ronu jinle ko to ṣe e, ajo ki iya ma ku ni iya ṣe, Alufa to sọrọ pe gbangba lasan nia ko purọ, ki babalawo ie mas rì aye "wẹrẹ" iyaiyawo lo ṣe owo fun iyara lọ ki alufa to ja wọn, babalawo wa ro ṣe" Bi a ko ba ri adun a o fi odidẹ ṣebọ" O kuku fi iyawo di iyaiyawo.

Ju gbogbo re lọ Ọgbẹni Yesufu Aṣiyanbi yio lọ mu suru ni, bi o ba binu o le 'o ṣe Oluwa, gẹgẹ bi ọrọ Bibeli, Jakọbu ori 1 ẹsẹ 20—26 Ofo ọni ki iṣe ọlamirẹ. Ki Olodumare pese iyawo rere dipọ o.

Emi ni
T. O. Kufielẹ
IFỌNLA-VILLAGE

### IDAHUN SI IBERE ỌGBẸNI I. O. ARO

Inu mi yio dun ti ẹ ba le gba mi laye lati dahun ibere Ọgbẹni I. O. Aro ti Ebute metta ti o jade ninu Iwe Irohin Yoruba ti 17/3/52.

(1) Ohun ti o rọ ju omi lọ ni afẹfẹ (afẹgun).

(2) Ohun ti o le fo ju ẹiyẹ lọ ni ọkọ ofurufu.

(3) Ohun ti o dun ni ju ọmọ lọ ni alafia.

Emi ni
Eliz Olu Adẹmuyiwa
EKO

(2)

Idahun temi si ibere na ni:—

(1) Afẹfẹ ni o rọ ju omi lọ.

(2) Oju ni o le fo ju ẹiyẹ lọ.

(3) Iyawo ẹni ni o dun ni ju ọmọ ẹni lọ, idi eyi nipe ma fẹ mi l'aya ni a ngbọ a ki igbọ ma fẹ mi l'ọmọ.

Emi ni
D. A. Adeọla
Adifa Street—ILỌRIN

(3)

Idahun temi si ibere na ni:—

(1) Iwa tabi suru.

(2) Ọkan tabi ẹmi.

(3) Alafia.

Ohun ti mo fi dahun ibere yi bayi nipe ẹnikẹni o ba ni alafia ohun gbogbo ni o ni, ati pe agba ti o ba ni suru ni ile rẹ nkan fun omọde ati pe ilu-ki-ilu ti enia ba ti mọ ẹsẹkẹsẹ ti o ba ti rante rẹ ni ẹmi rẹ yio ti fo da ibẹ.

Emi ni
J. B. Ogundipẹ
ABẸOKUTA

### MARTIN ATI OYINLOYE JANỌ

Nipa Idahun Ọgbẹni E. O Martins ti 120 Clifford St., Yaba ati ti Peter A Oyinloye ti Irorẹ ti o jade ni ọjọ kẹta oṣu kejila ọdun to kọja yi si ibere mi nipa "Oke Sioni."

Mo dupẹ pe idahun na ba ibere mi mu, owe awọn Baba wa kan tun sọ pe "Asọrọigbesi ni baba adanu" ẹ ṣe, mo dupẹ o.

Mo si tun fi eyi kẹwọ lati dupẹ lọwọ Ọgbẹni Samuel Ayandeji Onilu—Faaji ti Accra fun ayẹsi, apọnle ati inawo ti o ṣe fun mi ni akoko ipade Ogbomọsho Parapọ ti a ṣe ni Accra Gold Coast ni 14-15/2/52.

Emi ni
Joseph Ladipọ Ojo
CAPE COAST G. C.

E MAA POLOWO
Ọja nyin ninu
Iwe Irohin Yoruba

KO SI OTUTU MỌ




O fẹrẹ jẹ pe ni ẹsẹkẹsẹ na ti o ba lo "Mentholatum" ni otutu ti alọ. Fi si iho imu Fi pa ọna-ọfun ati aiya. Bi o ba ti bẹrẹ si fa orun itura "Mentholatum" sinu ni gbogbo idọti agbari ati ti imu a si bẹrẹ si ijade a si fun aiya ni alafia a ti tun mas mi dẹradẹra. Tete lọ ra idẹ tabi agolo "Mentholatum" kan loni. Fi pa aiya ki o si ti bọ imu.

Bere fun Mentholatum gan an, Eyiti o jẹ pe awọn Mentholatum Co, Ltd. (Est. 1889) Slough, England nikan ni nwọn nṣe e.

## AKIYESI PATAKI

Eyi ni lati fi kede fun gbogbo ẹnyin onkawe wa wipe ti ẹ ba nkọwe si wa ki ẹ ma kọ ọ yanju, nitoripe ọpọlọpọ ni awọn iwe (Letters and News) ti a nri gba lati idalẹ, ti o si jọ wipe idaji ni a o ri ka ninu rẹ.

Nipa bayi gbogbo anfani ti iba ti irufẹ inu iwe bẹ e jade ti nari sibẹ nayen, nigbati a ko le tẹ ẹ jade fun gbogbo aiye ka.

Fun awọn ti o nbinu pe iwe nwọn ko tete njade a tun fi eyi ṣe alaye fun nyin pe ohun ti o nfa iyẹn nipe iwe ti a nri gba ni arin ọsẹ kan le ni igba (200)

A ki gbogbo nyin patapata. Aunde ara o ma jẹ o

OLOTU

E MAA KA IWE Irohin Yoruba NIGBAGBOGBO

